eyi ti ododo ngbé. (Isa 65:17; 66:22; Ifh 21:1.)

**Ọrọ ipari ati igbani-niyanju.**

14. Nitori naa, olufẹ, bi ẹyin ti nreti iru nkan wọnyìí, ẹ mura gírí, ki a lè ba yin ni alaafia ni àìlábàwọ́n, ati ni àìlábùkù loju rẹ̀. (2 Pet 1:10; 1 Kor 15: 58; Filp 2:15.)

15. Ki ẹ si maa kà á si pe, sùúrù Oluwa wa igbala ni; bi Paulu pẹlu, arakunrin wa olufẹ, ti kọwe si yín, gẹgẹ bi ọgbọn ti a fifun un; (ẹsẹ 6; 1 Kor 3:10; Ef 3:3.)

16. Bi o ti nsọ̀rọ̀ nkan wọnyìí pẹlu ninu ìwé rẹ̀ gbogbo ninu eyi ti ohun miran ti o ṣoro lati yé ni gbé wà, eyi ti awọn òpè ati awọn alaiduro nibikan nló, bi wọn ti nló iwe- mímọ́ iyoku, si iparun ara wọn (ẹsẹ 14; Heb 5:11; 2 Pet 2:14; ẹsẹ 2.)

17. Nitori naa ẹyin olufẹ, bi ẹyin ti mọ̀ nkan wọnyìí tẹlẹ̀, ẹ maa kiyesara, ki a má baa fi ìṣìnà awọn eniyan buburu fà yín lọ, ki ẹ si ṣubú kuro ni iduro-ṣinṣin yin. (1 Kor 10:12; 2 Pet 2: 18; Ifh 2:5.)

18. Ṣugbọn ẹ maa dàgbà ninu oore-ọfẹ ati ninu ìmọ̀ Oluwa ati Olugbala wa Jesu Kristi; ẹni ti ogo wà fún nisinsinyìí ati títí lae. Amin.

62

# JOHANU KINNI

**(A.D. 90)**

ORI 1.

**Ọ̀rọ̀ Ìṣáájú.**

EYÍ ti o ti wà ni àtètèkọ́ṣe, ti awa ti gbọ́, ti awa ti fi ojú wa rí, ti awa sì ti tẹjúmọ́, ti ọwọ́ wa sì ti dìmú, niti Ọ̀rọ̀ ìyè; (Jhn 1:1,14; 2 Pet 1:16; Jhn 20:27.)

2. Ìyè naa si ti farahàn, awa sì ti ri i, awa sì njẹ́rìí, awa sì nsọ niti ìyè ainipẹkun naa fun yin, ti o ti nbẹ lọdọ baba, ti o si farahàn fun wa; (Jhn 1:1–4; Rom 16:20; Jhn 21:24.)

3. Eyi ti awa ti rí, ti awa sì ti gbọ́ ni awa nsọ fun yin, ki ẹ̀yin pẹlu lè ni ìdàpọ̀ pẹlu wa: nitootọ́ idapọ wa si nbẹ pẹ̀lú Baba, ati pẹlu Ọmọ rẹ̀ Jesu Kristi. (A.A. 4:20; 1 Kor 1:9.)

4. Awa sì kọwe nkan wọnyìí si yin, ki ayọ̀ yin lè di kíkún. (1 Jhn 2:1; Jhn 3:29.)

**Títọ ipa ọ̀nà ododo.**

5. Eyi si ni iṣẹ́ ti awa ti gbọ́ lẹnu rẹ̀ ti awa si njẹ́ fun yin, pe ìmọ́lẹ̀ ni Ọlọrun, òkùnkùn kò sì sí lọdọ rẹ̀ rárá. (1 Jhn 3:11.)

6. Bi awa bá wi pe awa ni ìdàpọ̀ pẹlu rẹ̀, ti awa sì nrìn ninu òkùnkùn, awa nṣèké, awa kò si ṣe otitọ́: (2 Kor 6:14; Jhn 8:55; 3:21.)

7. Ṣugbọn bi awa bá nrìn ninu ìmọ́lẹ̀, bi oun ti nbẹ ninu ìmọ́lẹ̀, awa ní idapọ pẹlu ara wa, ẹ̀jẹ̀ Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀ nwẹ̀ wá nù kuro ninu ẹ̀ṣẹ̀ gbogbo. (Heb 9:14; 1 Pet 1:19; Ifh 1:5.)

8. Bi awa bá wí pe awa kò ni ẹ̀ṣẹ̀, awa tan ara wa jẹ, òtítọ́ kò sí ninu wa. (Job 15:14; Owe 20:9; Jms 3:2; 1 Jhn 2:4.)

9. Bi awa bá jẹwọ ẹ̀ṣẹ̀ wa, olootọ ati olododo ni oun lati dari ẹ̀ṣẹ̀ wa jì wá, ati lati wẹ̀ wá nù kuro ninu aiṣododo gbogbo. (Psm 51:2.)

10. Bi awa ba wi pe awa kòì tîì dẹ́ṣẹ̀, awa mu un ni èké, ọ̀rọ̀ rẹ̀ ko sí ninu wa. (1 Jhn 5:10; 2:14.)

ORI 2.

EYIN ọmọ mi, iwe nkan wọnyìí ni mo kọ si yin, ki ẹ ma baa dẹ́ṣẹ̀. Bi ẹnikẹni bá sì dẹ́ṣẹ̀, awa ni alagbawi lọdọ Baba, Jesu Kristi olododo: (Rom 8:34; Heb 7:25.)

2. Oun sì ni ètùtù fun ẹ̀ṣẹ̀ wa: ki si i ṣe fun tiwa nikan, ṣugbọn fun ti gbogbo aráyé pẹlu. (Rom 3:25; Jhn 1:29.)

3. Nipa eyi ni a si mọ̀ pe awa mọ̀ ọ́n, bi awa ba npa ofin rẹ̀ mọ́.

4. Ẹni ti o ba wi pé, "Emi mọ̀ ọ́n", ti kò si pa ofin rẹ̀ mọ́, èké ni, otitọ kò si ninu rẹ̀.

5. Ṣugbọn ẹnikẹni ti o ba npa ofin rẹ̀ mọ́, lara rẹ̀ ni a gbe mu ifẹ Ọlọrun pé nitootọ. Nipa eyi ni awa mọ̀ pé awa nbẹ ninu rẹ̀. (Jhn 14:23; 1 Jhn 1:29.)

6. Ẹni ti o ba wi pe oun ngbe inu rẹ̀, oun naa pẹlu si yẹ lati maa rìn gẹgẹ bí oun ti rìn. (Jhn 15:4; 1 Pet 2:21.)

**Títọ ipa ọ̀nà ìfẹ.**

7. Ẹyin olufẹ, ki i ṣe ofin titun ni mo nkọ̀wé rẹ̀ si yin, ṣugbọn ofin atijọ́ ti ẹ̀yin ti ní ní atetekọṣe. Ofin atijọ ni ọ̀rọ̀ naa ti ẹ̀yin ti gbọ́. (1 Jhn 3:2; 2 Jhn 5; 1 Jhn 3:11.)

8. Pẹlupẹlu, ofin titun ni mo nkọwe rẹ̀ si yin, eyi ti i ṣe òtítọ́ ninu rẹ̀ ati ninu yin, nitori òkùnkùn nkọja lọ, ìmọ́lẹ̀ òtítọ́ si ti ntàn. (Ef 5:8; 1 Tess 5:5; Jhn 1.9.)

9. Ẹni ti o bá sì wí pe oun nbẹ ninu ìmọ́lẹ̀, ti o si korira arakunrin rẹ̀, o nbẹ ninu òkùnkùn titi fi di isinsinyìí. (2 Pet 1:9.)

10. Ẹni ti o ba fẹran arakunrin rẹ̀, o ngbe inu ìmọ́lẹ̀, kò sì sí ohun ìkọ̀sẹ̀ ninu rẹ̀. (1 Jhn 3:14; ẹsẹ 11.)

11. Ṣugbọn ẹni ti o bá korira arakunrin rẹ̀ o ngbe inú òkùnkùn, o sì nrìn ninu okùnkùn, kò si mọ ibi ti oun nrè, nitori ti òkùnkùn ti fọ́ ọ loju. (Jhn 12:35.)

12. Emi nkọ̀wé si yin, ẹ̀yin ọmọ mi, nitori ti a dari ẹ̀ṣẹ̀ yin ji yin nitori orukọ rẹ̀. (Luk 24:47.)

13. Emi nkọ̀wé si yin, ẹ̀yin baba, nitori ti ẹ̀yin ti mọ ẹni ti o wà ni atetekọṣe, Emi nkọ̀wé si yin, ẹ̀yin ọdọmọkunrin, nitori ti ẹ̀yin ti ṣẹgun ẹni buburu náà. Emi nkọ̀wé si yin, ẹ̀yin ọmọ mi, nitori ẹ̀yin ti mọ Baba. (1 Jhn 1:1; ẹsẹ 14.)

14. Emi kọ̀wé si yin, ẹ̀yin baba, nitori ti ẹ̀yin ti mọ ẹni ti o wà ni atetekọṣe. Emi kọ̀wé si yin, ẹ̀yin ọdọmọkunrin, nitori ti ẹ̀yin ni agbara, ti ọ̀rọ̀ Ọlọrun si duro ninu yin, ti ẹ si ṣẹgun ẹni buburu náà. (1 Jhn 1:1; Ef 6:10; Jhn 5:38.)

15. Ẹ máṣe fẹran ayé, tabi ohun ti nbẹ ninu ayé. Bi ẹnikẹni ba fẹran ayé, ifẹ ti Baba kò sí ninu rẹ̀. (Rom 12:2; Matt 6:24; Jak 4:4.)

16. Nitori ohun gbogbo ti nbẹ ninu ayé, ifẹkufẹ ti ara, ati ifẹkufẹ ti oju, ati irera ti ayé, ki i ṣe ti Baba, bikoṣe ti ayé. (Rom 13:14; Owe 27:20; Jms 4:16.)

17. Ayé si nkọja lọ, ati ifẹkufẹ rẹ̀: ṣugbọn ẹni ti o ba nṣe ifẹ Ọlọrun ni yoo duro laelae. (1 Kor 7:31.)

**Títọ ipa ọ̀nà igbagbọ ododo.**

18. Ẹnyin ọmọ mi, igba ìkẹhìn ni eyi: bi ẹ̀yin si ti gbọ́ pe Aṣòdìsí-Kristi nbọ̀wá, ani nisinsinyìí Aṣòdìsí-Kristi pupọ ni nbẹ; nipa eyi ti awa fi mọ̀ pe igba ìkẹhìn ni èyìí. (1 Pet 4:7; 1 Jhn 4:1,3.)

19. Wọn ti ọdọ wa jáde, ṣugbọn wọn ki i ṣe ara wa; nitori wọn ìbá ṣe ara wa, wọn iba bá wa duro: ṣugbọn wọn jade ki a lè fi wọn hàn pé gbogbo wọn ki i ṣe ara wa. (A.A. 20:30; Matt 24:24; 1 Kor 11:19.)

20. Ṣugbọn ẹ̀yin ní ìfòróró-yàn lati ọdọ Ẹni-Mímọ́ wá, ẹ̀yin si mọ ohun gbogbo. (2 Kor 1:21; A.A. 3:14; 1 Jhn 14:26.)

21. Emi kọ̀wé si yin kii ṣe nitori pe ẹ̀yin kò mọ òtítọ́, ṣugbọn nitori ti ẹ̀yin mọ̀ ọ́n, ati pe kò si èké ninu òtítọ́. (2 Pet 1:12; 1 Jhn 3:19.)

22. Tani èké, bikoṣe ẹni ti o ba sọ pe Jesu ki i ṣe Kristi? Eleyìí ni Aṣòdìsí-Kristi, ẹni ti o ba sẹ́ Baba ati Ọmọ.

23. Ẹnikẹni ti o ba sẹ́ Ọmọ, oun naa ni kò gba Baba: ṣugbọn ẹni ti o ba jẹwọ Ọmọ, o gba Baba pẹlu. (Jhn 14:7.)

24. Nigba naa jẹ ki eyi ti ẹ ti gbọ́ ni àtètèkọ́ṣe maa gbe inu yin. Bi eyi ti

ẹ̀yin ti gbọ́ ni àtètèkọ́ṣe ba ngbe inu yin, ẹ̀yin o si duro pẹlu ninu Ọmọ ati ninu Baba. (2 Jhn 6; Jhn 14:23.)

25. Eyi si ni ileri naa ti o ti ṣe fun wa, ani ìyè ainipẹkun. (Jhn 17:3.)

26. Nkan wọnyìí ni mo kọwe si yin niti awọn ti ntàn yín jẹ. (2 Jhn 7.)

27. Ṣugbọn ìfòróró-yàn ti ẹ̀yin ti gba lọwọ rẹ̀, o ngbe inu yin, ẹ̀yin kò tún ní pe ẹnikan nkọ yin: ṣugbọn ìfòróró-yàn naa nkọ yin ni ohun gbogbo ti o jẹ òtítọ́, ti ki si i ṣe èké, ani gẹgẹ bi o si ti kọ́ yin, ẹ maa gbe inu rẹ̀. (Jhn 14:26,17.)

28. Ati nisinsinyìí, ẹ̀yin ọmọ mi, ẹ maa gbe inu rẹ̀; pe, nigba ti oun o ba farahàn, ki a lè ni igboya niwaju rẹ̀, ki oju má sì tì wá niwaju rẹ̀ ni igba wíwá rẹ̀. (1 Jhn 3:2,21; 4:17; Mk 8:38; 1 Tess 2:19.)

29. Bi ẹ̀yin ba mọ̀ pe olododo ni oun, ẹ mọ pe a bi olukuluku ẹni ti nṣe ododo nipa rẹ̀. (1 Jhn 3:7,9; 4:7.)

ORI 3.

**Ìgbọràn ninu ìṣe.**

Ẹwo iru ifẹ ti Baba fi fẹ́ wa, ti a fi npe wa ni ọmọ Ọlọrun; bẹẹ ni a sàà jẹ. Nitori eyi ni ayé kò ṣe mọ̀ wá, nitori ti kò mọ ọn. (Jhn 1:12; 16:3.)

2. Olufẹ, ọmọ Ọlọrun ni awa nṣe nisinsinyìí, a koi ti i fihàn bi awa o ti rí: awa mọ̀ pe, nigba ti oun ba farahàn, a o dabi rẹ̀: nitori awa o ri i, ani bi oun ti rí. (Rom 8:15; 2 Kor 4:17; Rom 8:29; 2 Pet 1:4; 2 Kor 3:18.)

3. Olukuluku ẹni ti o ba sì ní ireti yìí ninu rẹ̀, nwẹ ara rẹ̀ mọ́, ani bi oun ti mọ́.

4. Ẹnikẹni ti o ba ndẹ́ṣẹ̀ o nrú ofin pẹlu: nitori ẹ̀ṣẹ̀ ni riru ofin. (Rom 4:15; 1 Jhn 5:17.)

5. Ẹ̀yin si mọ̀ pe, oun farahàn lati mu ẹ̀ṣẹ̀ kuro; ẹ̀ṣẹ̀ kò sì sí ninu rẹ̀. (Isa 53:5,6; 2 Kor 5:21.)

6. Ẹnikẹni ti o ba ngbe inu rẹ̀ ki i maa dẹ́ṣẹ̀; ẹnikẹni ti o ba sì ndẹ́ṣẹ̀ kò ri i, bẹẹ ni kò mọ̀ ọ́n.

7. Ẹ̀yin ọmọ mi, ẹ máṣe jẹ́ ki ẹnikẹni tàn yín: ẹni ti o ba nṣe òdodo, o jasi olódodo, gẹgẹ bi oun ti jẹ olódodo. (1 Jhn 2:1,26,29.)

8. Ẹni ti o ba ndẹ́ṣẹ̀ ti Eṣu ni; nitori lati àtètèkọ́ṣe ni Eṣu ti ndẹṣẹ̀. Nitori eyi ni Ọmọ Ọlọrun ṣe farahàn, ki o lè pa iṣẹ́ Eṣu run. (Jhn 8:44; 16:11; Heb 2:14.)

9. Ẹnikẹni ti a ti ipa Ọlọrun bí, ki i maa dẹ́ṣẹ̀; nitori ti iru rẹ̀ ngbe inu rẹ̀: kò sì lè dẹ́ṣẹ̀ nitori pe a ti ti ipa Ọlọrun bi i. (1 Jhn 5:18; 1 Pet 1:23.)

10. Ninu eyi ni awọn ọmọ Ọlọrun nfarahàn, ati awọn ọmọ Ẹ̀sù: ẹnikẹni ti kò ba nṣe òdodo ki i ṣe ti Ọlọrun, ati ẹni ti kò féràn arakunrin rẹ̀. (1 Jhn 2:29.)

**Ifẹ ninu Ìṣe.**

11. Nitori eyi ni iṣẹ́ ti ẹ̀yin ti gbọ́ ni àtètèkọ́ṣe, pe ki awa fẹran ara wa. (1 Jhn 1:5; Jhn 13:34,35; 2 Jhn 5.)

12. Ki i ṣe bi Kaini,ti i ṣe ẹni buburu, ti o si pa arakunrin rẹ̀. Nitori kinni o si ṣe paa? Nitori ti ìṣe tirẹ̀ jẹ́ buburu, ṣugbọn ti arakunrin rẹ̀ si jẹ ododo.

13. Ki ẹnu máṣe yà yín, ẹ̀yin ará mi, bi ayé bá korira yin. (Jhn 15:18.)

14. Awa mọ̀ pe awa ti rekọja lati inu ikú sinu ìyè, nitori ti awa fẹran awọn ará. Ẹni ti kò ba ni ìfẹ́ o ngbe inu ikú. (Jhn 5:24; 1 Jhn 2:9,11.)

15. Ẹnikẹni ti o ba korira arakunrin rẹ̀ apaniyan ni: ẹ̀yin si mọ̀ pe kò si apaniyan ti o ni ìyè ainipẹkun lati maa gbe inu rẹ̀. (Matt 5:21,22; Jhn 8:44; Gal 5:20,21.)

16. Nipa eyi ni awa mọ ifẹ nitori ti o fi ẹ̀mí rẹ̀ lélẹ̀ fun wa: o si yẹ ki awa fi ẹ̀mí wa lelẹ fun awọn ará. (Jhn 3:16; 13:1; 15:13.)

17. Ṣugbọn ẹni ti o bá ni ohun ìní ayé, ti o si ri arakunrin rẹ̀ ti o ṣe alaini, ti o si sé ilẹkun ìyọ́nú rẹ̀ mọ́ ọn, bawo ni ifẹ Ọlọrun ṣe ngbe inu rẹ̀? (Deut 15:7; 1 Jhn 4:20.)

18. Ẹyin ọmọ mi, ẹ máṣe jẹ ki a fi ọ̀rọ̀ tabi ahọ́n féràn, bikoṣe ni ìṣe ati ni òtítọ́. (Rom 12:9; Jms 1:22.)

19. Ati nipa eyi ni awa o mọ̀ pe àwa

jẹ́ ti òtítọ́, ati pé awa o si dá ara wa loju niwaju rẹ̀. (1 Jhn 2:21.)

20. Ninu ohunkohun ti ọkàn wa bá ndá wa lẹbi; nitori pe Ọlọrun tobi ju ọkàn wa lọ, o si mọ ohun gbogbo. (1 Kor 4:4.)

21. Olufẹ, bi ọkàn wa kò bá dá wa lẹbi, njẹ awa ni ìgboyà niwaju Ọlọrun. (1 Jhn 5:14.)

22. Ati ohunkohun ti awa bá bèèrè, ni awa nri gbà lọdọ rẹ̀, nitori ti awa npa ofin rẹ̀ mọ́, awa si nṣe awọn nkan ti o dara loju rẹ̀. (Matt 7:7; 21:22; 1 Jhn 2:8.)

23. Eyi si ni ofin, rẹ̀, pe ki awa gba orukọ Jesu Kristi Ọmọ rẹ̀ gbọ́, ki a si fẹran ara wa, gẹgẹ bi o ti fi ofin fun wa. (1 Jhn 2:8.)

24. Ẹni ti o ba si pa ofin rẹ̀ mọ́ ngbe inu rẹ̀, ati oun ninu rẹ̀. Ati nipa eyi ni awa mọ̀ pé o ngbe inu wa, nipa Ẹmi ti o fifun wa. (Rom 8:9; 1 Jhn 4:13.)

## ORI 4.

**Igbagbọ ninu ìṣe.**

OLUFẸ, ẹ máṣe gba gbogbo ẹ̀mí gbọ́, ṣugbọn ẹ dán awọn ẹ̀mí wò bi wọn ba ṣe ti Ọlọrun: nitori awọn woli èké pupọ ti jade lọ sinu ayé. (Matt 24:4; 2 Pet 2:1; 1 Jhn 2:18.)

2. Eyi ni ẹ o fi mọ Ẹ̀mí Ọlọrun: gbogbo ẹmi ti o ba jẹwọ pé, Jesu Kristi wá ninu ara, ti Ọlọrun ni: (1 Kor 12:3; 1 Jhn 2:23.)

3. Gbogbo ẹ̀mí ti kò sì jẹ́wọ́ pé, Jesu Kristi wá ninu ara, ki i ṣe ti Ọlọrun: eyi si ni ẹmi Aṣodisi-Kristi naa, ti ẹ̀yin ti gbọ pé o nbọ̀, ati nisinsinyìí o si ti de sinu ayé. (2 Jhn 7; 1 Jhn 2:22; 2 Tess 2:7.)

4. Ẹ̀yin ọmọ mi, ti Ọlọrun ni yín, ẹyin sì ti ṣẹgun wọn: nitori ẹni ti nbẹ ninu yin tobi ju ẹni ti nbẹ ninu ayé lọ. (1 Jhn 5:4; Jhn 12:31.)

5. Ti ayé ni wọn, nitori naa ni wọn ṣe nsọ̀rọ̀ bi ẹni ti ayé, ayé si ngbọ ti wọn. (Jhn 3:31; 15:19.)

6. Ti Ọlọrun ni awa: ẹni ti o ba mọ Ọlọrun o ngbọ́ ti wa: ẹni ti ki i ṣe ti Ọlọrun kò ni gbọ ti wa. Nipa èyí ni awa mọ̀ ẹmi òtítọ́, ati ẹmi èké. (Jhn 8:47; 1 Kor 14:37; Jhn 14:17; 1 Tim 4:1.)

**Orisun Ìfẹ́.**

7. Olufẹ, ẹ jẹ́ ki a fẹran ara wa: nitori ifẹ ti Ọ̀dọ̀ Ọlọrun wá; ati gbogbo ẹni ti o ba ni ìfẹ́, a bi i nipa ti Ọlọrun, o si mọ Ọlọrun. (1 Jhn 3:10,11.)

8. Ẹni ti kò bá ní ìfẹ́ kò mọ Ọlọrun: nitori pé ifẹ ni Ọlọrun. (ẹsẹ 16.)

9. Nipa eyi ni a gbe fi ifẹ Ọlọrun hàn ninu wa, nitori tí Ọlọrun rán Ọmọ bibi rẹ̀ nikanṣoṣo si ayé, ki awa lè yè nipasẹ rẹ̀. (Jhn 3:16; 1 Jhn 5:11.)

10. Ninu eyi ni ìfẹ wà, ki i ṣe pe awa fẹ Ọlọrun, ṣugbọn oun fẹ́ wa, o si rán Ọmọ rẹ̀ lati jẹ ètùtù fun ẹ̀ṣẹ̀ wa. (Rom 5:8,10; 1 Jhn 2:2.)

11. Olufẹ, bi Ọlọrun ba fẹ wa bayìí, o yẹ ki a fẹran ara wa pẹlu. (Jhn 3:16; 15:12.)

12. Ẹnikẹni kò ri Ọlọrun nigba kan rí. Bi awa ba fẹran ara wa, Ọlọrun ngbe inu wa, a si mu ifẹ rẹ̀ pé ninu wa. (Jhn 1:18; 1 Tim 6:16; 1 Jhn 2:5.)

13. Nipa eyi ni awa mọ̀ pe awa ngbe mu rẹ̀, ati oun ninu wa, nitori ti o ti fi Ẹmi rẹ̀ fun wa. (1 Jhn 3:24.)

14. Awa ti rí, a si jẹ́rìí, pé Baba ran Ọmọ rẹ̀ lati jẹ́ Olugbala fun arayé. (Rom 10:9.)

15. Ẹnikẹni ti o ba jẹ́wọ́ pé Jesu Ọmọ Ọlọrun ni, Ọlọrun ngbe inu rẹ̀, ati oun ninu Ọlọrun.

16. Bayìí ni awa mọ̀, ti a si gba ifẹ ti Ọlọrun ní si wa gbọ́. Ifẹ ni Ọlọrun; ẹni ti o ba sì ngbe inu ifẹ o ngbe inu Ọlọrun, ati Ọlọrun ninu rẹ̀. (ẹsẹ 8; 1 Jhn 3:24.)

17. Ninu èyí ni a mu ifẹ ti o wa ninu wa pé, ki awa baa lè ni ìgboyà ni ọjọ́ ìdájọ́: nitori pe bi oun ti rí, bẹẹ ni awa sì rí ni ayé yìí. (1 Jhn 2:28.)

18. Ìbẹ̀rù kò sí ninu ifẹ; ṣugbọn ifẹ ti o pé nlé ibẹru jade: nitori ti ibẹru ní ìyà ninu. Ẹni ti o bẹru ko pe ninu ifẹ. (Rom 8:15; ẹsẹ 12.)

19. Awa fẹran rẹ̀ nitori oun ni o kọ́ fẹran wa. (ẹsẹ 10.)

20. Bi ẹnikẹni bá wí pe, "Emi fẹran Ọlọrun", ti o si korira arakunrin rẹ̀, èké ni: nitori ẹni ti kò fẹran arakunrin rẹ̀ ti o ri, bawo ni yoo ti ṣe lè fẹran Ọlọrun ti oun kò rí? (1 Jhn 2:4; 1:6; 3:17.)

21. Ofin yìí ni awa si ri gbà lati ọwọ́ rẹ̀ wa, pe ẹni ti o ba fẹran Ọlọrun ki o fẹran arakunrin rẹ̀ pẹlu.

## ORI 5.

**Ìṣẹ́gun nipa igbagbọ.**

OLUKULUKU ẹni ti o ba gbagbọ pe Jesu ni Kristi, a bi i nipa ti Ọlọrun: ati olukuluku ẹni ti o fẹran Ẹni ti ó bi nì, ó fẹran ẹni ti a bi nipasẹ Rẹ̀ pẹlu. (Jhn 1:12; 1 Jhn 2:22,23; Jhn 1:13; 8:42.)

2. Nipa eyi ni awa mọ̀ pe awa fẹran awọn ọmọ Ọlọrun, nigba ti a ba fẹran Ọlọrun, ti a si npa ofin rẹ̀ mọ́. (1 Jhn 2:5.)

3. Nitori eyi ni ifẹ Ọlọrun, pé ki awa pa ofin rẹ̀ mọ́: ofin rẹ̀ kò sì nira. (Jhn 14:15; 1 Jhn 2:5; 2 Jhn 6.)

4. Nitori olukuluku ẹni ti a bi nipa ti Ọlọrun o ṣẹgun ayé: eyi si ni iṣẹgun ti o ṣẹgun ayé, ani igbagbọ wa. (Jhn 16:33.)

5. Tani ẹni ti o ṣẹgun ayé, bikoṣe ẹni ti o gbagbọ pe Ọmọ Ọlọrun ni Jesu jẹ?

**Igbagbọ nipasẹ Ọmọ Ọlọrun.**

6. Eyi ni ẹni tí o wá, nipa omi ati ẹ̀jẹ̀, Jesu Kristi, kii ṣe nipa omi nikan, bikoṣe nipa omi ati ẹjẹ. (Jhn 19:34.)

7. Ati pe Ẹ̀mí ni o si njẹri, nitori pe òtítọ́ ni Ẹmí. (Jhn 15:26.)

8. Nitori pe awọn mẹta ni o njẹri, Ẹmi, omi, ati ẹ̀jẹ̀: awọn mẹtẹẹta si wà ni ìṣọkan. (Matt 18:16.)

9. Bi awa ba ngba ẹ̀rí eniyan, ẹ̀rí Ọlọrun tobi ju: nitori ẹ̀rí Ọlọrun ni eyi pé O ti jẹri niti Ọmọ rẹ̀. (Jhn 8:17,18; Matt 3:16,17.)

10. Ẹni ti o ba gba Ọmọ Ọlọrun gbọ́, o ni ẹ̀rí ninu ara rẹ̀: ẹni ti kò bá gba Ọlọrun gbọ, o ti mu un ni èké; nitori kò gba ẹri naa gbọ ti Ọlọrun jẹ niti Ọmọ rẹ̀. (Rom 8:16; Gal 4:6; Jhn 3:33.)

11. Ẹri naa si ni eyi pe Ọlọrun fun wa ni ìyè ainipẹkun, ìyè yìí si nbẹ ninu Ọmọ rẹ̀. (1 Jhn 2:25; Jhn 1:4.)

12. Ẹni ti o ba ni Ọmọ, o ni ìyè; ẹni ti kò ba si ni Ọmọ Ọlọrun, kò ni ìyè. (Jhn 3:36.)

**Awọn ohun idaniloju igbagbọ.**

13. Nkan wọnyìí ni mo kọwe rẹ̀ si yin ani si ẹ̀yin ti o gba orukọ Ọmọ Ọlọrun gbọ; ki ẹ̀yin lè mọ̀ pe ẹ̀yin ni ìyè ainipẹkun, ani fun ẹ̀yin ti o gba orukọ Ọmọ Ọlọrun gbọ́. (Jhn 20:31; 1 Jhn 1:1,2.)

14. Eyi si ni ìgboyà ti awa ni niwaju rẹ̀, pe bi awa ba bèèrè ohunkohun gẹgẹ bi ifẹ rẹ̀, o ngbọ́ ti wa: (1 Jhn 3:21,22; Matt 7:7.)

15. Bi awa ba si mọ̀ pe o ngbọ́ ti wa, ohunkohun ti awa bá bèèrè, awa mọ pe awa ri ìbéèrè ti awa ti bèèrè lọdọ rẹ̀ gba.

16. Bi ẹnikẹni bá rí arakunrin rẹ̀ ti ndẹ́ṣẹ̀ ti ki i ṣe si ikú, oun yoọ bèèrè, Ọlọrun yoo si fun un ni ìyè, ani, fun awọn ti ndẹ́ṣẹ̀ ti kii ṣe si ikú. Ẹ̀ṣẹ̀ kan nbẹ si iku: emi kò wi pe ki oun gbadura fun èyí. (Jms 5:15; Heb 6:4,6.)

17. Gbogbo aiṣododo ni ẹ̀ṣẹ̀: ẹ̀ṣẹ̀ kan nbẹ ti ki i ṣe si ikú. (1 Jhn 3:4.)

18. Awa mọ pe ẹnikẹni ti a bi nipa ti Ọlọrun kii maa dẹ́ṣẹ̀: ṣugbọn ẹni ti a bi nipa ti Ọlọrun a maa pa ara rẹ̀ mọ́, ẹni buburu kò ni lè fọwọkàn án. (1 Jhn 3:9; Jhn 14:30.)

19. Awa mọ pe ti Ọlọrun ni wá, ati gbogbo ayé ni o wa lábẹ́ agbara ẹni buburu naa.(1 Jhn 4:6; Gal 1:4.)

20. Awa si mọ pe Ọmọ Ọlọrun dé, o sì ti fi òye fun wa, ki awa lè mọ̀ ẹni ti i ṣe òtítọ́, awa si nbẹ ninu ẹni ti i ṣe otitọ, ani ninu Ọmọ rẹ̀, Jesu Kristi. Eyi ni Ọlọrun otitọ, ati ìyè ainipẹkun. (Luk 24:45; Jhn 17:3; Ifh 3:7.)

21. Ẹyin ọmọ mi, ẹ pa ara yin mọ́ kuro ninu òrìṣà. (1 Kor 10:14.)